## (1) Suratul-Fãtihah

**1.** Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun[1].

**2.** Gbogbo ọpẹ ti Ọlọhun ni, Olutọju gbogbo ẹda[2].

**3.** Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.

**4.** Olukapa ọjọ idajọ.

**5.** Irẹ nikan ni awa yio ma sin, ọdọ Rẹ nikan ni a o ma tọrọ iran lọwọ.

**6.** Tọ wa si ọna tãrà.

**7.** Ọna awọn ẹniti Ose idẹra Rẹfun, pẹlu titẹle aṣẹ Rẹ ati ijọsin fun[3] Ẹ laijẹ (ọna) awọn ti Obinu Si, bẹni laijẹ ọna awọn ti nwọn sina[4].

## سُورَةُ الفَاتِحَة

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ ١

ٱلۡحَمۡدُ لِلَّهِ رَبِّ ٱلۡعَٰلَمِينَ ٢

ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ ٣

مَٰلِكِ يَوۡمِ ٱلدِّينِ ٤

إِيَّاكَ نَعۡبُدُ وَإِيَّاكَ نَسۡتَعِينُ ٥

ٱهۡدِنَا ٱلصِّرَٰطَ ٱلۡمُسۡتَقِيمَ ٦

صِرَٰطَ ٱلَّذِينَ أَنۡعَمۡتَ عَلَيۡهِمۡ غَيۡرِ
ٱلۡمَغۡضُوبِ عَلَيۡهِمۡ وَلَا ٱلضَّآلِّينَ ٧

---

[1] Alanu-julọ, Onikẹ. Aladipele-ẹsan.

[2] Rabba ni itumọ ti o pọ, ṣugbọn nitori ki ọrọ ma gun ju lori rẹ ni a fi le tumọrẹ si Oluwa Olutọju. Itumọ ti awọn onitafsiri miran fun Rabba ni Olure, Ẹniti ntọju nkan (ẹda) lati iṣẹlẹ rẹ titi yio fi dagba de opin idagba-soke rẹ.

[3] Awọn ti Ọlọhun se idẹra fun ni awọn Anabi Ọlọhun ati awọn olododo, ati awọn to kusi oju ogun ẹsin Islam, ati awọn oluse rere.

[4] Awọn ti Ọlọhun binu si ni awọn «Yahudi», fun pipe ti nwọn pe Annabi Issa nirọ, ti nwọn kosi gba fun u. Awọn «Nasãra» ni awọn ti o ṣina tara, fun pipe ti nwọn pe Issa ni ọmọ Ọlọhun.